HOSPITAL CONTACT DETAILS

# IDANWO HALT-IT NAA
# ALAYE NIPA IWADI NAA

**Akọle Iwadi**: Tranexamic acid fun itọju ẹjẹ ti o nda lati inu ifun ati ikun: ohun agbaye aimuniṣiṣẹntẹle, idanwo iwadi itọju ti o farasin fun olutọju ati alaisan.
**Nọmba ibi iwadi**: xx
**ẹya inu oju ewe:** 2.0 [Nigeria] 23/08/2017

**Ile iwosan yi nkopa ninu iwadi lati wa awọn itọju ti o peye fun awọn ti o ni aisan ìṣẹ̀jẹ̀ lati inu ìfun ati ikùn.**

## Ọkan ninu awọn ohun ti o wa ni nisalẹ yi ba yin mu:

1) Ẹ jẹ́ alaisan ti ẹjẹ nda lati inu ifun ati ikun rẹ. Nigbati ara yin ko ya rara, a fi orukọ yin si ara awọn olukopa iwadi yi. Ni bayi, a nbere lọwọ yin pe ki ẹ gbàárò lati kopa ninu iyoku iwadi yi
2) Ẹ jẹ́ alaisan ti ẹjẹ nda lati inu ifun ati ikun rẹ. Nigbati ara yin ko ya rara, a fi orukọ yin si ara awọn olukopa iwadi yi. Ni bayi, a nbere lọwọ yin pe ki ẹ gbàárò lati kopa ninu iyoku iwadi yi.
3) Ẹ jẹ aṣoju alaisan ti ẹjẹ nda lati inu ifun ati ikun rẹ. A nbere lọwọ yin wipe ki ẹ pinnu fun alaisan boya alaisan naa yoo le kopa ninu iwadi yi. Ẹ le ṣe ipinnu yin lori wipe, ti ẹ ba ro wipe alaisan naa yoo faramọ ikopa ninu iwadi yi ti o ba jẹ wipe ara rẹ ya lati le da ṣe ipiinnu naa.

## Kini ohun ti iwe ìléwọ́ yi wa fun?

Ki ẹ to pinnu lati darapọ mọ iwadi yi, a fẹ ki ẹ mọ idi iwadi yi ati ohun ti yoo nilo. Ọkan lara awọn alábàṣiṣẹ́pọ̀ wa yoo ṣe àgbéyẹ̀wò iwe ìléwọ́ yi pẹlu yin, yoo si dahun ibere ti ẹ ba ni. A ni ero wipe eyi yoo gba to ogun iṣẹju. Ẹ lee ba awọn miran sọrọ nipa iwadi yi ti ẹ ba fẹ.

## Kini èrèdí iwadi yi?

A fẹ lati mọ boya itọju ti o dara ju wa fun iṣẹjẹ lati inu ìfun ati ikùn. A ni ireti wipe iwadi itọju naa (ogun kan ti a npe ni tranexamic acid), eyi ti o nṣe iranwọ fun ẹjẹ titadi oju ọgbẹ, yoo le mu ki iṣẹjẹ lati inu ifun ati ikun ki o dinku. Ṣugbọn o ṣeeṣe ki o fa itadi ẹjẹ ni awọn ibi ti a ko ti nilo rẹ.
Tranexamic acid ki iṣe ogun titun. A ti loo lati ran awọn ti ẹjẹ nda lara wọn lẹyin iṣẹ́ abẹ tabi ijanba kan. A ni ero wipe itọju yi yoo ṣe ohun ti o dara pupọ ju ibi lọ ti a ba lo fun awọn alaisan ti o ni iṣẹjẹ lati inu ifun ati ikun, ṣugbọn a ko ti mọ eyi daju.

## Kini idi ti a fi bi mi lati kópa?

Ẹyin (alaisan naa) ní ẹ̀jẹ̀ ti o nṣan jade lati inu ifun ati ikun yin wa ti o nilo itọju ni kiakia. Dokita yin ni ero wipe ẹ lee kopa ninu iwadi yi, ṣugbọn kikopa tabi aikopa rẹ wa ni ọwọ yin. Ti ẹ ba kopa, ẹ óò jẹ ọkan ninu awọn ẹgbẹrun mejila eniyan (12,000 ) ti o ni iṣẹjẹ lati inu ifun ati ikun ti wọn nkopa ninu iwadi yi kaakiri agbaye

## Alaisan kan ko lee wa ninu iwadi yi ti:

- Dokita naa ba ro wipe idi kan wa ni pàtó ti a **ko gbọdọ** fi fun ni tranexamic acid
- Dokita naa ba ro wipe idi kan wa ni pàtó ti a **gbọdọ** fi fun ni tranexamic acid
- Ti alaisan naa ko ba ti dagba

A pe yin (alaisan naa) lati kopa ninu iwadi yi nitori ẹ ko si ninu eyikeyi ninu ipo ti o wa ni oke yi.

## Njẹ mo ni lati kopa bi?

Rara. Ipinnu lati kopa tabi lati ma kopa wa ni ọwọ yin. Ti ẹ ko ba fẹ kopa, dokita yin yoo si ma tẹsiwaju lati maa ṣe aájò yin ati lati maa fun yin ni gbogbo itọju ti ẹ nilo.

## Bawo ni iwadi naa ṣe nṣiṣẹ?

A ko mọ boya ti a ba lo tranexamic acid papọ mọ gbogbo itọju ti a saba ma nṣe fun iṣẹjẹ lati inu ifun ati ikun yoo dara si tabi ko ni dara. Ọna ti a le fi mọ eyi ni lati ri bi awon ti a fun ni itọju yi ṣe ri, ki a si ṣe àfiwé wọn pẹlu awọn ti ko gba itọju ogun yi. Ẹgbẹ́ kan ninu awọn ti wọn nkopa ninu iwadi yi yoo gba itọju ti a nṣe iwadi rẹ (tranexamic acid). Ẹgbẹ keji yoo gba itọju ti o jọọ (itọju ti ko ni ògùn naa ninu). Ìyàn lati mọ ẹgbẹ ti alaisan kan yoo wa jẹ ohun ti a yan ni àìníṣíṣẹ̀ntẹ̀lé, ati pe ẹnikọkan ni anfanni ti o dọgba lati wa ninu eyikeyi ninu ẹgbẹ mejeeji yi. Itọju iwadi naa ati itọju ti ko ni ogun naa ninu rara ri bakanna, fun idi eyi, eyin ati dokita yin ko ni mọ ẹgbẹ ti ẹ wa.

## Kini yoo ṣẹlẹ si mi ti mo ba darapọ mo iwadi yi?

Gbogbo itọju ti ẹ maa ngba lati ṣe iranwọ fun iṣẹjẹ yin ni ẹ o gba. Ẹ o si tun gba ọkan ninu itọju iwadi naa (tranexamic acid tabi eyi ti a kan fi di gẹrẹwu ti ko ni ninu). Ẹ óò bẹrẹ itọju yi lẹsẹkẹsẹ. Ẹ óò gba si ara lati inu omi ti a fa si yin lara fun wakati mẹrin lelogun (24 hours) . Ọfẹ ni itọju iwadi yi. Ẹ ko nilo ati ṣe awọn afikun ayẹwo tabi lati wa ni ile iwosan ju igba ti o yẹ ki ẹ wa lọ nitori iwadi naa.

A óò fun yin ni iwe ilewọ yi lati tọju pamọ a óò si tun bere ki ẹ bu ọwọ lu iwe ifohunsi. A si tun fẹ lati fi lẹta ṣọwọ́ si dokita yin lati jẹ ki o mọ wipe ẹ nkopa ninu iwadi naa.

## Kini yoo ṣelẹ lẹyin eyi?

A óò fẹ lati mọ nipa ipo ilera yin lẹyin ti ẹ kuro ni ile-iwosan. Ki ẹ to lọ si ile, a óò fun yin ni kaadi kan ti ẹ óò mu lọwọ pẹlu yin. Ti ẹ ba ri dokita tabi nọsi Kankan fun aisan kan larin oṣu kan ti ẹ wa si ile iwosan, ki ẹ fi kaadi yi han wọn.

## Njẹ ipalara wa fun mi ti mo ba kopa?

Awọn iwadi miran ti dá ni àbá pe iwadii itọju (tranexamic acid) kii ṣe okunfa itadi ẹjẹ ati pe ko si ohun ti ko dara Kankan ti o ṣẹlẹ pẹlu lilo rẹ fun igba kukuru, ṣugbọn a ko mọ boya eyi yoo jẹ bakanna pẹlu awọn eniyan ti o wa ni iru ipo yin. Dokita yin yoo wo yin yoo si fun yin ni iwosan ti o dara julọ ti o wa bi iṣoro Kankan ba ṣẹlẹ. Wọn óò si tun sọ fun awọn eniyan ti nṣe iwadi naa.

## Njẹ ere wa fun mi ti mo ba kopa?

A ko mọ boya iwadi yi yoo ṣe iranwọ fun yin. Ṣugbọn yoo ran awọn dokita lọwọ lati ṣe itọju awọn ti o ba ni iṣẹjẹ lati inu ifun ati ikun ni ọjọ iwaju.

## Njẹ mo lee yi ipinnu mi nipa kikopa pada bi?

Bẹeni. Ti ẹ ba ni iyipada ọkan nipa kikopa, ohun ti ẹ kan ni lati ṣe ni wipe ki ẹ sọ fun dokita yin pe ẹ ko fẹ kopa ninu iwadi yi mọ. Ẹ le ṣe eleyi nigbakigba. Dokita yin yoo maa tẹsiwaju lati ṣe áájò yin, yoo si tun fun yin ni gbogbo itọju ti ẹ nilo. A ni ireti pe ẹ óò ṣi gba wa ni aye lati lo alaye nipa bi ẹ ṣe tẹsiwaju si, ṣugbọn ti ẹ ko ba fẹ ki a lo, ẹ jọwọ ẹ sọ fun dokita yin.

## Awọn alaye wo ni ẹ óò gba nipa mi?

A óò ṣe akọsilẹ awọn alaye nipa iṣẹjẹ yin, awọn ogun ti ẹ gba ati bi ara yin ṣe ri. Oṣiṣẹ olu ile iṣẹ wa ni Lọndọnu lee fẹ lati gba ẹda iwe ifohunsi ti ẹ bu ọwọ́ lù lati lee ri daju pe iwadi yi nlọ gẹgẹbi bi o ti tọ.

## Njẹ alaye nipa mi yoo jẹ ohun aṣiri bi?

Gbogbo alaye ti a ba gba nipa yin yoo jẹ ohun aṣiri. Awọn eniyan ti wọn lee ni áàyè lati wo alaye naa yoo jẹ awọn dokita ti wọn nṣe iwadi naa, awọn oṣiṣẹ olu ile-iṣẹ ni ilu Lọndọnu ati awọn alaṣe ti wọn nṣe ayẹwo lati ri wipe iwadi na nlọ gẹgẹbi o ṣe tọ.

Dokita yin yoo fi awọn alaye kan nipa yin ṣọwọ si awọn ẹgbẹ ti o nṣe ayẹwo yi ni ilu Lọndọnu, wọn yoo si tọju rẹ pamọ si ibi ti o ni abo. Awọn alaye nipa yin yoo wa ni ipamo ti o ni abo yatọ si awọn alaye iwadi ti o kù, a óò si bajẹ larin ọdun marun ti iwadi ba ti pari.

Aóò tẹ èsì iwadi naa jade ninu iwe iroyin eto ilera ki awọn dokita ti wọn ku le kọ ẹkọ nibẹ. Alaye nipa yin ko ni si ninu iroyin iwadi yi, ko si si ọna kankan ti ẹnikẹni fi lee da yin mọ.

Awọn akojọpọ alaye naa yoo wa fun ilo awọn oluwadi ni gbogbo agbaye ki o le wulo lati mu ki imọ eto ilera ati itọju alaisan ki o dara si. Alaye nipa yin ko ni si ninu iroyin iwadi yi, ko si si ọna kankan ti ẹnikẹni fi lee da yin mọ.

## Tani o nṣe agbatẹru iṣuna owo fun iwadi yi?

Ijoba ilẹ United Kingdom ni o ṣe ipese owo fun iwadi yi. Dokita yin ati awọn alaisan ko gba owo Kankan ninu iwadi yi. Awọn iṣuna owo ti o rọ̀mọ́ ṣiṣe iwadi yi nikan ni ipese yoo wa fun.

## Tani o ti yẹ iwadi yi wo?

Lati le dabobo ohun ti ẹ nifẹ si, gbogbo iwadi ti a ṣe ni ile iwosan yi ni awọn ẹgbẹ kan ti o da wa ti a npe ni Research Ethics Committee kan ṣe ayẹwo rẹ. A ti ṣe agbeyẹwo iwadi yi, wọn si ti fun ni ami moyege lati ọwọ (Insert Name)ti Research Ethics Committee. Ti ẹ ba ni ibeere Kankan lori awọn ẹtọ yin tabi ẹ ni ero wipe awọn ẹtọ yin gẹgẹbi olukopa ti di itẹmọlẹ, ẹ le kan si alaga ni adirẹsi ti o wa ni isalẹ yi:

| | |
|---|---|
| Orukọ alaga | |

| | |
|---|---|
| Adirẹsi | |

Iwadi yi ti gba ami moyege ni Naijiria lati ọwọ:

*Oludari naa, Awọn Ẹka idari Eto Imuṣedeede ati Iforukọsilẹe*
*Àjọ ti o nṣoju fun iṣakoso ilo Ounjẹ ati Ogun lilo (NAFDAC)*
*445, Herbert Macaulay Way*
*Yaba, Lagos, Nigeria*
*Ẹrọ ibanisọrọ: 01 477 2452*

## Njẹ mo lee mọ awọn esi iwadi yi bi?

Iwadi na yẹ ki o pari ni ọdun ẹgbẹrun meji ati ogun (2020), ti ẹ ba nifẹ si ati mọ apapọ esi iwadi naa ni ṣókí lẹyin ti o ba ti pari, ẹ jọwọ, ẹ jẹ ki dokita ti o nṣe itọju yin mọ. Ẹ si tun le ṣe abẹwo si oju ẹrọ ayelujara iwadi yi lati le mọ bi iwadi naa ṣe ntẹsiwaju ni (haltit.Lshtm.ac.uk).

## Tani mo lee ba sọrọ ti mo ba ni awọn ohun miran ti o ndun mi ni ọkan?

Ti ẹ ba ni awọn ibeere tabi awọn ohun miran ti o ndun yin ni ọkan nipa ipele yiowu ninu iwadi yi, ki ẹ bere lati ba awọn dokita iwadi yi sọro, wọn o si sa ipa wọn lati dahun awọn ibeee yin. Dr [fi orukọ rẹ si] ni o wa ni akoso iwadi yi ni ile iwosan yi. Ẹ lee kan si dokita naa ni:

| | |
|---|---|
| Adirẹsi | |
| Ẹrọ ibanisọrọ | |

Ẹsi tun lee kan si Olọla Oludari Eto ilera (Chief Medical Director) ti ile iwosan yi:

| | |
|---|---|
| Orukọ Oludari naa | |
| Adiresi | |
| Ẹrọ ibanisọrọ | |

Ti inu yin ko ba dun sibẹ ti ẹ si fẹ fi ẹhonu yin han gẹgẹbi àṣà, ẹ lee ṣe eyi nipasẹ ilana ifi ẹhonu han ti ile iwosan. Ẹ jọwọ ẹ bere ẹkunrẹrẹ alaye lọwọ awọn oluwadi.

Awọn dokita ati awọn ẹgbẹ idanwo áṣewò kan ni London School of Hygiene & Tropical Medicine (Fasiti ti Lọndọnu). Ẹ lee kàn si wọn n:

| | |
|---|---|
| Address | HALT-IT Trial Coordinating Centre, London School of Hygiene & Tropical Medicine, Room 180, Keppel Street, London WC1E 7HT, United Kingdom |
| Telephone | +44 (0)20 7299 4684 |

## Kini ohun ti mo tun ni lati mọ?

Ti ohunkohun ti ko dara ba ṣẹlẹ ti o fa ipalara fun yin, ti o si jẹ wipe iwa àìbìkítà ẹnikan ni o ṣe okunfa rẹ, nigbanaa idi wa fun yin lati beere fun ìsanpadà fun ìtùlójú. London School of Hygiene and Tropical Medicine naa, ti wọn nṣe eto iwadi yi yoo dahun fun ohun ti ẹ ba beere fun ipalara ti ẹ ni nipasẹ aibikita ẹnikan nigbati ẹ nkopa ninu iwadi yi.

A rọ̀ yin lati bere awọn ibere ti ẹ ba fẹ, ṣaju iwadi, nigbati iwadi nlọ lọwọ ati nigba ti o ti pari. Ti ẹ ba ni ibeere Kankan nipa iwadi yi, ẹ jọwọ ẹ ba dokita tabi nọsi iwadi yin sọrọ, yoo ṣeéṣe fun wọn lati fun yin ni awọn alaye ti o peye nipa ogun (awọn ogun) / ilana (awọn ilana) ni ṣiṣẹntẹle ti o gba. Ti ẹ ba fẹ ka iwadi ti ayẹwo yi duro le lori, ẹ jọwọ e beere lọwọ dokita yin tabi nọsi.